# KIYE SARA KIWỌ

# MABA GBAGBE OLUWA

# ỌLỌRUN RẸ

**Deut. 6:12**

## Ọna Ọlọrun Kan Ṣoṣo To Ja Sọrun

"Ki a máṣe tàn nyin jẹ; a kò le gàn Ọlọrun: nitori ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ká" —Galatia 6:7.

"Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ" —Romu 6:23.

"Niwọn bi a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ̀kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ" Heberu 9:27.

"Ohun ẹ̀ru ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọrun alãye' Heberu 10:31.

"Awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi eyi" —Heberu 2:3.

## Gbogbo Enia Ni Ẹlẹṣẹ

"Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" —Romu 3:23.

"Gẹgẹ bi a ti kọ ọ pe, Kò si ẹniti iṣe olododo, kò si ẹnikan" —Romu 3:10.

## Ṣugbọn Arọpo Wa

"Kristi ti kú nitori ẹ̀ṣẹ wa gẹgẹ bi iwe-mimọ́ ti wi" —1 Korinti 15:3.

"Jesu Oluwa . . . ẹniti a fi tọrẹ ẹ̀ṣẹ wa, ti a si jinde nitori idalare wa"—Romu 4:24, 25.

Yoa-1

"Nitori igbati awa jẹ alailera, li akokò ti o yẹ, Kristi kú fun awa alaiwàbi-Ọlọrun" Romu 5:6.

"Sugbọn Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa" —Romu 5:8.

## Ẹbun Ni Igbala

"Nwọn si wi fun u pe, Gbà Jesu Kristi Oluwa gbọ́, a o si gbà ọ là, iwọ ati awọn ara ile rẹ́ pẹlu" —Ise Awan Aposteli 16:31.

"Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́" —Johannu 1:12.

"Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa" —Romu 6:23.

"Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ mà bá ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" —Johannu 3:16.

## Ronunpiwada Ẹṣẹ Rẹ

"Oluwa wipe, wá nisisiyi, ki ẹ si jẹ ki a sọ asọyé pọ̀: bi ẹ̀ṣẹ nyin ba ri bi òdodó nwọn o si fun bi òjo-didì; bi nwọn pọ́n bi àlãri, nwọn o dabi irunagutan" —Isaiah 1:18.

"Bikoṣepe ẹnyin ronupiwada, gbogbo nyin ni yio ṣegbé bẹ̆ gẹgẹ" —Luku 13:3.

## Ẹjẹ Kristi Nikan Lo Weni Mọ Kuro Ninu Ẹṣẹ Gbogbo

"Ninu ẹniti awa ni irapada wa nipa ẹjẹ rẹ̀, idariji ẹ̀ṣẹ wa, gẹgẹ bi ọrọ̀ ore-ofẹ rẹ̀"
Efesu 1:7.

"

"Ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" —1 Johannu 1:7.

"Ará, njẹ bi a ti ni igboiya lati wọ̀ inu ibi mimọ́ nipasẹ ẹ̀jẹ Jesu" —Heberu 10:19.

**Word Of Truth**, P.O Box 1126, Kaduna, Nigeria